ABLE BODIED ADULT WITHOUT DEPENDENTS (ABAWD)

# Àwọn Àmúyẹ Oúnjẹ Pàtó:
# Ohun Tí O ní Láti Mọ̀ Láti Tọ́jú Àwọn Ànfàní Rẹ

**Basic Food Eligibility Requirements: What You Need to Know to Keep Your Benefits**

## Àwọn ànfàní rẹ jẹ́ onígbà díẹ̀ tí o kò bá ṣiṣẹ́

A rí ọ bíi Àgbà Tó Dápé Láì Ní Ọmọ (ABAWD) fún Oúnjẹ Pàtó nítorí o lágbára láti ṣiṣẹ́ o kò sì ní ọmọ nínú ẹbí rẹ.

O le gba àwọn ànfàní Oúnjẹ Pàtó fún oṣù mẹ́ta nínú oṣù 36 kọ̀ọ̀kan tí o kò bá kójú òṣùwọ̀n fún iṣẹ́.

## Bí o ti le tọ́jú àwọn ànfàní Oúnjẹ Pàtó rẹ

O gbọ́dọ̀ ṣe ọ̀kan tàbí ọ̀pọ̀ àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí láti tọ́jú àwọn ànfàní rẹ fún ju oṣù mẹ́ta lọ:

- Parí iṣẹ́ ìfarajì nípasẹ̀ ètò Iṣẹ́ ní oṣoṣù. Iye owó ànfàní rẹ yóò pinnu iye wákàtí tí wàá fi fara rẹ jì láti tọ́jú àwọn ànfàní oúnjẹ rẹ.
- Ṣiṣẹ́ fún bíi ó kéré jù wákàtí 20 láàrín ọ̀sẹ̀ kantàbí wákàtí 80 lóṣù  kan
- Kópa nínú ètò iṣẹ́ kan tí ìjọba fọwọ́sí tàbí ètò ìkẹ́kọ̀ọ́ bíi:
  - Ìkẹ́kọ̀ọ́ àti Iṣẹ́ Oúnjẹ Pàtó (BFET). Fún àlàyé síi lọ sí www.dshs.wa.gov/bfet;
  - Àwọn ètò tó wà nínú Òfin Ànfàní àti Ọgbọ́-inú Iṣẹ́ (WIOA). Fún àlàyé síwájú síi lọ sí https://www.dshs.wa.gov/esa/community-services-offices/wioa;
  - AmeriCorps VISTA; tàbí
  - Ipa-ọ̀nà Àìle Sọ Èdè Gẹ̀ẹ́sì Dáradára (LEP).

## Àwọn ìdènà sí ìkópa

Kàn sí wa tí o kò bá le kópa fún ó kéré jù wákàtí 80 lóṣù nítorí o:

- Jẹ́ abarapá tàbí ní àrùn ọpọlọ;
- Ń gba àwọn ànfàní láti Ibi-iṣẹ́ àti Ilé-iṣẹ́ (L&I), Ìtọ́jú Arúgbó, tàbí ìdójútòfò abarapá aládàáni;
- Ń gbé ní àyíká tí kò fàyè gba iṣẹ́, bíi aláìnílé onígbà pípẹ́;
- Ń tọ́jú àwọn tí kò le tọ́jú ara wọn nítorí ọjọ́-orí tàbí abarapá;
- Ń kópa nínú ìtọ́jú tó dá lórí kẹmika tàbí ètò ìtọ́jú abẹ́lé;
- Ti bèrè tàbí gba àwọn ànfàní àìníṣẹ́;
- Ti forúkọ sílẹ̀ ní ilé-ìwé ó kéré jù ìlàjì àkókò; tàbí
- Ń gba àwọn ànfàní Ìrànlọ́wọ́ Owó Adúró tàbí Owó Dídọ́gba.

## Àwọn ohun tí o gbọ́dọ̀ jábọ̀

O gbọ́dọ̀ sọ fún wa tí:

- O kò bá le parí iye wákàtí ìkópa tí o nílò láàrín oṣù kan.
- Iṣẹ́ kéré sí wákàtí 20 lọ́sẹ̀.
- Owó àpawọlé mọ̀lẹ́bí rẹ ti kọjá òdíwọ̀n inú WAC 388-478-0060.

O le rí ọ̀pọ̀ àlàyé nípa àwọn àmúyẹ ABAWD ní www.dshs.wa.gov/abawd.

Pè wá sórí 1-877-501-2233 tí o bá ní ìbéèrè, nílò ìrànlọ́wọ́ láti sopọ̀ mọ́ ètò ìkẹ́kọ̀ọ́ kan, tàbí ní láti jábọ̀ àwọn àyípadà.

O le ṣàbẹ̀wò wa ní www.washingtonconnection.org láti bèrè fún àwọn ànfàní, fa àtúnyẹ̀wò kalẹ̀ tàbí jábọ̀ àwọn àyípadà.